**30.** (Ki o) si wọnu ọgba-idẹra Mi.

وَٱدۡخُلِي جَنَّتِي ﴿٣٠﴾

## *(90) Suratul - Baladi*

سُورَةُ البَلَدِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aşakẹ ọrun.*

بِسۡمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحۡمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Mo fi ilu yi bura.

لَآ أُقۡسِمُ بِهَٰذَا ٱلۡبَلَدِ ﴿١﴾

**2.** Atipe ojẹ ẹtọ fun ẹ ninu ilu yi (lati fi iya jẹ awọn alaigbagbọ-eyiun ni ọjọ isẹgun makkah).

وَأَنتَ حِلُّۢ بِهَٰذَا ٱلۡبَلَدِ ﴿٢﴾

**3.** Ati òbi ati ẹniti o bi.

وَوَالِدٖ وَمَا وَلَدَ ﴿٣﴾

**4.** Dajudaju Awa ti da enia sinu wahala.

لَقَدۡ خَلَقۡنَا ٱلۡإِنسَٰنَ فِي كَبَدٍ ﴿٤﴾

**5.** On ha nrò ni pe ẹnikẹni kò ni sa agbara le on lori ni?

أَيَحۡسَبُ أَن لَّن يَقۡدِرَ عَلَيۡهِ أَحَدٞ ﴿٥﴾

**6.** On sọpe: Mo ti padanu ọpọlọpọ owó.

يَقُولُ أَهۡلَكۡتُ مَالٗا لُّبَدًا ﴿٦﴾

**7.** On ha nro pe ẹnikankan kò ri on ni?

أَيَحۡسَبُ أَن لَّمۡ يَرَهُۥٓ أَحَدٌ ﴿٧﴾

**8.** Njẹ Awa kò ti şe oju meji fun u.

أَلَمۡ نَجۡعَل لَّهُۥ عَيۡنَيۡنِ ﴿٨﴾

**9.** Ati ahọn kan ati ètè meji.

وَلِسَانٗا وَشَفَتَيۡنِ ﴿٩﴾

**10.** Atipe Awa ti fi ọna meji ti o yanju mọ̀ ọ?

وَهَدَيۡنَٰهُ ٱلنَّجۡدَيۡنِ ﴿١٠﴾

**11.** Şugbọn kiloşe ti kò sure kò si oju ọna oke lati pan (Akabà).

فَلَا ٱقۡتَحَمَ ٱلۡعَقَبَةَ ﴿١١﴾

**12.** Kini o le mu ọ mọ ọna oke (Akabà) na.

وَمَآ أَدۡرَىٰكَ مَا ٱلۡعَقَبَةُ ﴿١٢﴾

**13.** (On na ni) ki o sọ ẹru di ọmọ.

فَكُّ رَقَبَةٍ ﴿١٣﴾

**14.** Tabi fifun (awọn enia) ni onjẹ ni ọjọ ebi.

أَوْ إِطْعَٰمٌ فِى يَوْمٍ ذِى مَسْغَبَةٍ ﴿١٤﴾

**15.** ọmọ-orukan ti o sunmọ ọ.

يَتِيمًا ذَا مَقْرَبَةٍ ﴿١٥﴾

**16.** Tabi talaka (ti aini sọdi agbejẽ) ti o di ẹni ilẽlẹ̀.

أَوْ مِسْكِينًا ذَا مَتْرَبَةٍ ﴿١٦﴾

**17.** Lẹhinna o wà ninu awọn ẹniti o gbagbọ ni ododo ti nwọn ngba awọn enia niyanju pe ki nwọn ni ifarada ti nwọn tun ngba awọn enia niyanju pe ki nwọn ṣe ãnú.

ثُمَّ كَانَ مِنَ ٱلَّذِينَ ءَامَنُوا۟ وَتَوَاصَوْا۟ بِٱلصَّبْرِ وَتَوَاصَوْا۟ بِٱلْمَرْحَمَةِ ﴿١٧﴾

**18.** Awọn wọnyi ni èrò ọwọ-ọtun.

أُو۟لَٰٓئِكَ أَصْحَٰبُ ٱلْمَيْمَنَةِ ﴿١٨﴾

**19.** Ṣugbọn awọn ẹniti nwọn ṣe aigbagbọ si awọn ãyah Wa, awọn ni èrò ọwọ osi.

وَٱلَّذِينَ كَفَرُوا۟ بِـَٔايَٰتِنَا هُمْ أَصْحَٰبُ ٱلْمَشْـَٔمَةِ ﴿١٩﴾

**20.** Lori wọn, ina ni yio bo wọn mọlẹ̀ (ti atilẹkun rẹ).

عَلَيْهِمْ نَارٌ مُّؤْصَدَةٌۢ ﴿٢٠﴾

## *(91) Suratul - Ṣamsi*

سُورَةُ الشَّمْسِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.*

بِسْمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحْمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Mo fi orùn bura ati imọlẹ̀ rẹ̀.

وَٱلشَّمْسِ وَضُحَىٰهَا ﴿١﴾

**2.** Ati oṣupa nigbati o (fi imọlẹ̀ rẹ̀) tẹle e (orùn).

وَٱلْقَمَرِ إِذَا تَلَىٰهَا ﴿٢﴾

**3.** Ati ọsan nigbati o ṣipaya (ọjọ).

وَٱلنَّهَارِ إِذَا جَلَّىٰهَا ﴿٣﴾